OFFICE OF THE CITIZEN OF THE FEDERAL REPUBLIC OF NIGERIA

# #OfficeOfTheCitizen
# Handbook

**A Guide to Your Rights, Responsibilities, and Civic Power in Nigeria**

(English)

*© 2025 Enough is Enough Nigeria. All rights reserved.*

*This **Office Of The Citizen** Handbook is the intellectual property of Enough is Enough Nigeria (EiE Nigeria). This document is intended for the use of citizens as a one-stop resource for understanding your role and achieving success in your "Office of the Citizen."*

*Unauthorized reproduction, distribution, or modification of this document, in whole or in part, without the express written permission of EiE Nigeria is strictly prohibited. This manual may not be used for commercial purposes or any activities not directly related to the #myLGA Project without prior consent.*

*Maiden Edition (October 2025)*

www.eie.ng . 0708 478 7788 . info@eienigeria.org
EiENigeria eieng.co/WhatsApp

NIGERIA CIVIL SOCIETY
SITUATIONROOM

in partnership with

UK International Development
Partnership | Progress | Prosperity

with support from UK Foreign, Commonwealth and Development Office (FCDO)

# Table of Contents


| | | |
|---|---|---|
| 1 | About the #OfficeOfTheCitizen Handbook | 1 |
| 2 | Your Rights & Responsibilities | 2 |
| 3 | Understanding Government | 5 |
| 4 | The Legislator | 7 |
| 5 | How to Recall a Legislator | 10 |
| 6 | Citizen Participation Tools | 13 |
| 7 | Practical Guides & Case Studies | 16 |
| 8 | Resources & Contacts | 18 |

# #OfficeOfTheCitizen Handbook

## A Guide to Your Rights, Responsibilities, and Civic Power in Nigeria

In Nigeria, the **highest** office in the land is not the President, the Governor, or any elected official. It is the **Office of the Citizen**. Every Nigerian carries this office by birth or naturalisation. It is through this office that we **vote**, hold leaders **accountable**, and **build** the kind of country we want.

Democracy is more than elections. It is the daily work of citizens asking questions, demanding answers, and playing their part in community development. **As a citizen, you are not powerless.**
You have rights that protect you, and responsibilities that guide you.

This handbook is your one-stop resource for understanding your role and achieving success in your **"Office of the Citizen."**

*"it is clear that until Nigerians understand*
*their rights and responsibilities and use*
*that knowledge to hold government accountable,*
*our society will continue to be unjust."*

**- Opeyemi Adamolekun**
(Executive Director, EiE Nigeria)



# 1 Your Rights & Responsibilities

## Your Rights

*(Fundamental Rights - Chapter IV, Sections 33-46 of the 1999 Constitution, as amended)*

As a Nigerian citizen, the Constitution guarantees that you have:

1. **Right to life** – no one has the power to take your life.
2. **Right to dignity of the human person** – you must not be subjected to torture, slavery, or degrading treatment.
3. **Right to personal liberty** – no one should arrest or detain you unlawfully.
4. **Right to fair hearing** – if accused of wrongdoing, you are entitled to a fair trial.
5. **Right to private and family life** – your privacy, home, and correspondence are protected.
6. **Right to freedom of thought, conscience, and religion** – you can believe, worship, and live according to your faith.
7. **Right to freedom of expression** – you can speak, write, and share ideas freely.
8. **Right to peaceful assembly and association** – you can gather with others, join unions, political parties, or civic groups.

9. **Right to freedom of movement** – you can live, travel, and work anywhere in Nigeria.

10. **Right to freedom from discrimination** – you must not be mistreated because of sex, religion, ethnicity, or background.

11. **Right to own property** – you can acquire, own, and transfer property anywhere in Nigeria.

*These rights are not just words on paper – they are your shield against abuse and your tool for participation.*

## Your Responsibilities

*(Duties of Every Citizen – Section 24 of the 1999 Constitution, as amended)*

Rights come with responsibilities. As a Nigerian citizen, you are expected to:

1. **Respect and defend Nigeria** – honour the Constitution, flag, national anthem, and lawful authorities.

2. **Be loyal to your country** – defend Nigeria if required, and contribute positively to its unity and progress.

3. **Respect the rights of others** – live peacefully with neighbours and honour the dignity of every person.

4. **Contribute to community development** – participate in efforts that improve your environment and society.

5. **Obey the law** – act justly and assist lawful authorities in maintaining peace.

6. **Pay your taxes honestly** – declare your income truthfully and pay what is due.

---

**Participate in governance** – **R**egister | **S**elect | **V**ote | **P**rotect (**RSVP**) and engage your representatives after elections.

*Being a good citizen means balancing what you are owed (rights) with what you owe (responsibilities).*





# 2 Understanding Government

*In Nigeria, the government is organised into three arms and three tiers.*

## The Three Arms of Government

1. **Executive** – implements laws and runs government day to day.
    a. **Federal:** The President and Ministers.
    b. **State:** The Governor and Commissioners.
    c. **Local:** The Local Government Chairman and Councillors.



2. **Legislature** – makes laws, approves budgets, and checks the executive.
    a. **Federal:** National Assembly *(Senate and House of Representatives).*
    b. **State:** State Houses of Assembly.
    c. **Local:** Local Government Councils.



3. **Judiciary** – upholds the mandates of the Constitution and resolves disputes generally according to law.
    a. **Federal:** Supreme Court, Court of Appeal, Federal High Courts.
    b. **State:** State High Courts and other lower courts.



*These arms work separately, but must also check and balance one another.*

## The Three Tiers of Government




1. **Federal Government** – handles issues affecting the whole country, like defence, foreign policy, currency, and large-scale infrastructure.

2. **State Government** – manages state matters like roads, secondary education, hospitals, and state budgets.

3. **Local Government** – closest to the people; responsible for primary education, primary health care, markets, roads, sanitation, and local development.

*Understanding who is responsible at each level helps you know where to take your demands.*



3

# The Legislature

## How It Works

*The legislature is the people's assembly. It makes laws, approves budgets, and holds the executive accountable. Legislators are your representatives - they speak and act on your behalf.*

### Nigeria's Legislative Houses

**1**

#### National Assembly

a. **Senate**

109 Senators (3 per state, 1 from FCT).

b. **House of Representatives**

360 members representing constituencies - population and land mass.

**2**

#### State House of Assembly

a. At least 24 members, depending on population and land mass/size.

b. Makes laws for the state and oversees the Governor.

**3**

#### Local Government Council

a. Made up of councillors representing wards.

b. Make bylaws for the Local Government and oversee the Chairman.

### What the Legislature Does

1. **Appropriations** – they pass the country and states' annual budgets.

2. **Lawmaking** – they make laws that promote peace, order and good government.

3. **Representation** – as elected officials, they represent their constituencies.

4. **Oversight** – ensure the executive arm of government is delivering on the projects for which monies have been appropriated.

5. **Consent to high-level appointments** – e.g. Ministers, Commissioners, Central Bank Governor, INEC chairman, etc.

## How a Bill Becomes Law

1. **First Reading** – bill is introduced; only the title is read.

2. **Second Reading** – members debate the general principles.

3. **Committee Stage** – detailed examination, possible amendments.

4. **Third Reading** – final version debated and passed.

5. **Transmission**:
   a. **National level:** sent to the other chamber (Senate - House of Reps).
   b. **State level:** remains in the House of Assembly.

6. **Assent** – President or Governor signs the bill into law.

7. **If vetoed/not assented** – the legislature can override with a two-thirds majority.

## Oversight Tools of the Legislature

1. **Questions** – legislators can question the executive on policies.

2. **Motions** – draw attention to issues and propose action.

3. **Investigations & Hearings** – committees can summon officials, investigate spending, and hold public hearings.

4. **Appropriation Control** – no spending without legislative approval.

## Citizen Engagement with the Legislature

1. Attend public hearings and make submissions.
2. Petition your legislator on issues that matter.
3. Monitor laws and budgets.
4. Use platforms like **ShineYourEye** to track and contact your representatives.
5. Visit your legislator in their constituency office.

*The legislature belongs to the people. If citizens don't engage, laws and budgets may not reflect their needs.*






4

# How to Recall a Legislator

## What It Means

*A recall is a constitutional tool that allows citizens to remove an elected legislator before the end of their term if they are not representing the people's interests. It is one of the strongest ways for citizens to hold lawmakers accountable.*

## Steps in the Recall Process

### 1. Petition by Voters



a. Registered voters in the legislator's constituency write a petition stating why they want the recall.

b. At least 50% of registered voters in the constituency must sign the petition.

### 2. Submission to INEC



a. The petition is submitted to the Independent National Electoral Commission (INEC).

b. INEC verifies the signatures to confirm that they belong to valid registered voters in the constituency.

### 3. Referendum (Voting)



a. If verification is successful, INEC conducts a referendum in the constituency.

b. All registered voters are asked: "Do you want this legislator recalled?"

c. The authenticity of submitted signatures or thumbprints is verified, and voting is conducted through an open-secret ballot under the Commission's regulations. Voters may only vote at their registered polling units.

d. If more than 50% of voters say YES, the legislator stands recalled.

e. If the recall is successful, INEC conducts a by-election to replace the recalled legislator.

## Who Can Be Recalled?

1. Members of the National Assembly (Senate and House of Representatives).
2. Members of the State Houses of Assembly.

*Governors and Presidents cannot be recalled. They can only be removed by impeachment by the legislators. Local government officials cannot be recalled either.*

## Challenges of Recall in Nigeria

1. Gathering signatures from 50% of registered voters is very difficult.
2. Many citizens are unaware of the process or their power to use it.
3. Politicians often use money, influence, or intimidation to frustrate recall attempts.
4. No legislator in Nigeria has been successfully recalled.

## Why the Recall Process Still Matters

1. Even if difficult, recall shows that citizens have the constitutional power to check representatives.
2. The process raises awareness and can pressure lawmakers to act better.
3. It teaches communities how to organise, mobilise, and demand accountability.

*Recall is one tool among many - petitions, protests, public hearings, and citizen campaigns are also ways to hold leaders accountable.*






5

# Citizen Participation Tools

*Democracy is not a spectator sport. Citizens have both the right and responsibility to take part in governance. These tools help you play your role effectively.*

Shine Your Eye

## Find & Engage Your Representatives

1. Visit ***www.shineyoureye.org***.
2. Enter your Polling Unit (PU) number, or search by state and local government, to find details of your representatives at all levels.



3. Get phone numbers, emails, and other contacts.
4. Share updated information so that all citizens benefit from accurate data *(syeinfo@eienigeria.org)*.

*Democracy works best when citizens know and engage their representatives.*

R S V P
REGISTER SELECT VOTE PROTECT

## Register I Select I Vote I Protect

1. **Register** – Ensure you are on the voters register and have your Permanent Voter's Card (PVC).
2. **Select** – Look beyond promises; examine candidates' **Character, Competence, Capacity, Courage** and **Compassion**.

3. **Vote** – Turn out on election day and cast your ballot.

4. **Protect** – Stay until votes are counted, report irregularities, and follow results. And then engage the elected official during the four years.

***RSVP** is not just for election day - it is a cycle of participation before, during, and after elections.*

## Permanent Voter's Card (PVC): Registration & Updates

Go to ***cur.inecnigeria.org*** or an INEC office to:

1. Register as a new voter.
2. Check your voter details to ensure accuracy.
3. Transfer your polling unit if you move to a new area.
4. Correct errors on your voter record.
5. Collect your PVC when it is ready.
6. Replace a lost or damaged card.

*INEC may suspend registration at certain times (e.g., close to an election). Always check online or at local offices for updates.*




Once you turn 18, you are eligible to register and vote in Nigeria.

If you are not registered, you cannot vote and others will determine who represents your community, LG, state and country on issues that matter to you.

*Your PU number is on the top-left.*
*Your VIN is the number on the top-right of your PVC.*

## Monitoring Elections

1. Stay at the polling unit until votes are counted.
2. Record results and share with your community.
3. Report incidents of malpractice through INEC hotlines or accredited civil society platforms.
4. Refuse vote-buying - your vote is your voice.



## Other Civic Tech Tools *(by EiE Nigeria and Partners)*

1. **LearnPolitics.ng** – providing comprehensive political education.
2. **#MissingInNG** (governi.ng) – report and track missing persons.
3. **Podus AI** – draft legal documents, solve problems, & get lawyers. Message 07067951851 on WhatsApp to get started.
4. **Tracka.ng** – report, follow, and track projects that are to be done, ongoing or abandoned in your community.
5. **Govspend.ng** – monitor the federal government's actual releases to its ministries, departments, and agencies, track recipients of government funds and contracts.

*These platforms bring governance closer to you - use them to stay informed and engaged.*

6

# Practical Guides & Case Studies

*Citizenship is not just about knowing your rights - it is about using them. Across Nigeria, communities have organised, asked questions, and made leaders act. These stories show what is possible when citizens engage.*

## Case Study 1:
## Clean Water for IDPs in Nasarawa *(#myLGA)*

In Ugya, Toto LGA (Nasarawa State), displaced families struggled daily to find clean water. Streams and wells exposed them to disease. In June 2025, through EiE's **#OOTCHelpDesk**, their cry reached the Local Government Chairman. A borehole was dug in the camp, giving residents safe drinking water for the first time.

**Lesson:** *Even the most difficult problems can be solved when citizens speak and leaders listen.*

## Case Study 2:
## Restoring Schools in Zamfara *(Office of the Citizen Radio)*

In Birnin Ruwa, Zamfara, children studied in crumbling classrooms with leaking roofs and no desks. In 2019, EiE's Office of the Citizen radio program gave the community a platform. The story went statewide, government officials visited, and a renovation contract was awarded. Today, schools are restored and children learn in safe classrooms.

**Lesson:** *A single broadcast can secure education for hundreds of children.*

## Case Study 3:
## Victory for Okada Riders in Enugu *(Office of the Citizen Radio)*

In Emene-Nkwubor, Enugu East LGA (2019), commercial motorcycle riders were being extorted by police under a false Okada ban. On OOTC Radio, riders shared their story live. EiE escalated it to the Commissioner of Police, who ordered all bikes released, stopped the extortion, and began investigations.

**Lesson:** *When injustice is exposed, even powerful institutions are forced to act.*

## Case Study 4:
## Reviving Healthcare in Osun *(Office of the Citizen Radio)*

Across Osun State, neglected healthcare centres left people without care. In 2019, OOTC Radio highlighted the decay. The government responded by rehabilitating centres, giving countless residents better access to healthcare.

**Lesson:** *Citizen voices can put health back on the agenda.*

## Practical Tips for Engagement

1. Always put demands in writing (letters, petitions, social media posts).
2. Work as a group - collective voices are stronger than individual ones.
3. Follow up persistently; accountability takes time.
4. Use media and technology to amplify your cause.
5. Stay peaceful and law-abiding in all actions.

# Resources & Contacts

*As an active citizen, you don't have to act alone. These platforms and organisations can support you with tools, information, and resources.*

## EiE Nigeria Platforms

1. **ShineYourEye.org** – Find and contact your elected representatives.
2. **myLGA.ng** – Learn about and monitor your Local Government.
3. **#MissingInNG (governi.ng)** – Report and track missing persons.
4. **RSVP.ng (Civic education)** – Register, Select, Vote, Protect.
5. **eienigeria.org** – Access our civic education, advocacy, and campaign resources.

| Organisation /Platform | Focus | Contact |
|---|---|---|
| **INEC** | *Election management, voter registration, PVCs, election results* | *www.inecnigeria.org cvr.inecnigeria.org* |
| **Tracka** | *Report, follow, and track projects that are to be done, ongoing or abandoned in your community.* | *www.tracka.ng Tracka Mobile App (available on the IOS and Android playstore)* |
| **Govspend** | *Monitor the federal government's actual releases to its ministries, departments, and agencies, track recipients of government funds and contracts.* | *www.govspend.ng* |
| **Podus AI** | *Draft legal documents, solve problems, & get lawyers.* | *Message 07067951851 on WhatsApp to get started* |
| **Yiaga Africa** | *Election observation, youth engagement, #NotTooYoungToRun* | *www.yiaga.org* |
| **CLEEN Foundation** | *Security, justice sector reform, police accountability.* | *www.cleen.org* |

*This handbook brings together content from EiE Nigeria's civic education resources, including the Office of the Citizen Passport, Constitution 101, Legislative Passport, and Recall Guide. It is designed for easy use at the grassroots level.*

# Publications







www.eie.ng/resources/publications/

# Publications







www.eie.ng/resources/publications/

# #OfficeOfTheCitizen

# ÌWÉ ATỌNI-SỌNÀ

**Ìtọ́sọ́nà sí àwọn Ẹ̀tọ́ rẹ, Ojúṣe rẹ àti Agbára rẹ ní Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà.**

(Èdè Yorùba)

*© 2025 Enough is Enough Nigeria. Gbogbo ẹ̀tọ́ wà ní ìpamọ́.*

*Ìwé Atọ́ni-sọ́nà ọ́fíísì ọmọ ìlú yìí jẹ́ ohun-ìní ìmọ̀ ti Enough is Enough Nigeria (EiE Nigeria). A ṣe àkọsílẹ̀ yìí fún lílo àwọn ọmọ ìlú gẹ́gẹ́ bí ibi kan ṣoṣo fún gbogbo ohun-èlò láti lóye ipò rẹ àti láti ṣàṣeyọrí nínú "Ọ́fíísì ọmọ-Ìlú" rẹ.*

*A ṣé lèèwọ̀ láti ṣe àdàkọ, pín tàbí láti yí àkọsílẹ̀ yìí padà, yálà ní odidi àbí apá rẹ̀ kan, láìgba àṣẹ ìwé kíkọ láti ọwọ́ àjọ EiE Nigeria. A kò gbọ́dọ̀ lo ìwé ìtọ́sọ́nà yìí fún èrè tàbí fún isẹ́ kankan tí kò bá isẹ́ àkànṣe #MyLGA mu láìgba àṣẹ ṣáájú.*

*Àtẹ̀jáde àkọ́kọ́ (oṣù kẹwàá /Ọ̀wàrà 2025).*

# Àkóónú ìwé


| | | |
|---|---|---|
| 1 | Nípa ìwé-ìléwọ́ Atọ́nisọ́nà #OfficeOfTheCitizen | 23 |
| 2 | Àwọn Ẹtọ́ àti Ojúṣe Rẹ | 24 |
| 3 | Mímọ̀ Nípa Ìjọba | 27 |
| 4 | Aṣòfin | 29 |
| 5 | Bí a ṣe lè yọ Aṣòfin kúrò (Recall) | 32 |
| 6 | Àwọn Irin-iṣẹ́ fún Ìkópa Ọmọ Ìlú | 34 |
| 7 | Àwọn Ìtọ́sọ́nà tó wúlò àti Àpẹẹrẹ Ìṣẹ̀lẹ̀ gidi | 38 |
| 8 | Àwọn Ohun-èlò àti Ìkànnì Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | 40 |

# Ìwé-Ìléwọ́ ọ́fíísì ọmọ-Ìlú

Èyí ni atọ́ka sí ẹ̀tọ́ rẹ, ojúṣe rẹ àti agbára rẹ ní Nàìjíríà.

Ní Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà, Ọ́fíísì tó lágbára jù kọ́ ni ti Ààrẹ, tàbí ti Gómìnà àbí ẹnikẹ́ni tí a dìbò yàn Bí kò ṣe ọ́fíísì ọmọ-ìlù. Gbogbo ọmọ Nàìjíríà ni ọ́fíísì yìí gbérù yálà ẹni tí ó fi orin wọ̀lú tí a bí sí ìlú yìí tàbí ẹni tí ó fi ẹsẹ rìn wọ̀lú ṣùgbọ́n tó ti di ọmọ-ìlù. Láti ara agbára ọ́fíísì yìí ni a fi ń dìbò, le béèrè fún ẹ̀tọ́ wá àti láti rọ Orílẹ̀-Èdè sí bí a ṣe fẹ́.

Ìṣejọba Alágbádá ju ìdìbò lọ. Isẹ́ gbogbo ìgbà ni fún àwọn ọmọ-ìlù láti Máa ṣe ìbéèrè, retí ìdáhùn àti láti kópa nínú ìdàgbàsókè àwùjọ. Gẹ́gẹ́ bi ọmọ-ìlù, Ó kìí ṣe aláìlágbára, ó ní ẹ̀tọ́ tó dàbò bò ẹ́, bẹ́ẹ̀ sì ni ó ní Ojúṣe tó ń ṣe Atọ́nà rẹ̀.

Ìwé-Ìléwọ́ yìí jẹ́ ohun àmúlò kan láti ní àgbọyé lórí ipa rẹ àti láti ni àṣeyọrí ní 'ọ́fíísì ọmọ-ìlù' rẹ.

*"Ó dájú pé àfi tí àwa ọmọ Nàìjíríà bá mọ Ẹ̀tọ́ wa àti iṣẹ́ tó tọ́ sí wa, tí a sì béèrè ìṣirò lọ́wọ́ ìjọba, ìyà àti ài òdodo kò ní kúrò ní ilẹ̀ yìí."*

**- Opeyemi Adamolekun**
(Executive Director, EiE Nigeria)



1

# Àwọn Ẹ̀tọ́ àti ojúṣe rẹ

## Àwọn Ẹ̀tọ́ rẹ

*(àwọn Ẹ̀tọ́ tó ṣe pàtàkì jù lọ orí IV, Ìpín 33-46 ti Ìwé-Òfin 1999 tí a ṣe àtúnṣe sí)*

Gẹ́gẹ́ bí ọmọ Nàìjíríà, Ìwé-Òfin fún ọ ní ìdánilójú pé o ní :

1. **Ẹ̀tọ́ láti wà láyé** - Ẹnikẹ́ni kò ní agbára láti gbẹ̀mí rẹ láìbófin mu.

2. **Ẹ̀tọ́ sí iyì fún ọmọ ènìyàn** - Ẹnikẹ́ni kò gbọ́dọ̀ fìyà jẹ ọ́, fi ọ sẹrú tàbí fi ọ́ sẹ̀sín.

3. **Ẹ̀tọ́ òmìnira ẹni** - Ẹnikẹ́ni kò gbọ́dọ̀ fi ọ sí àtìmọ́lé tàbí so ẹ mọ́lẹ̀ láìbófin mu.

4. **Ẹ̀tọ́ láti wí tẹnu rẹ** - Tí wọ́n bá fi ẹ̀sùn kan kàn ọ́, ó ní ẹ̀tọ́ láti wí tẹnu rẹ.

5. **Ẹ̀tọ́ láti dágbé àti sí ìbágbépọ̀ mọ̀lẹ́bí** – Ìpamọ́ra rẹ, ilé rẹ àti gbogbo ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ rẹ wà lábẹ́ àbò.

6. **Ẹ̀tọ́ sí òmìnira ìrònú, Ẹ̀rí-ọkàn àti ẹ̀sìn** – O le ní ìgbàgbọ́, ṣe ẹ̀sìn àti gbé ní ìlànà ìgbàgbọ́ rẹ.

7. **Ẹ̀tọ́ láti sọ èrò ọkàn rẹ** - O lè sọ̀rọ̀, kọ nǹkan àti pín èrò bo se wù ọ́.

8. **Ẹ̀tọ́ láti kójọ papọ̀ àti láti e ẹgbẹ́** – O le kójọ pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn, darapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́, ìjọ tàbí àjọ ìlú.

9. **Ẹ̀tọ́ láti rìn yan fanda kiri** – Ó lè gbé, rìnrìn àjò àti I ẹ́ níbikíbi ní Nàìjíríà.

10. **Ẹ̀tọ́ sí òmìnira níbi ẹlẹ́yàmẹ̀yà** – Wọn kò gbọdọ̀ fi ìyà jẹ ọ́ tàbí rẹ́ ọ jẹ nítorí pé ó jẹ́ akọ tàbí abo,ẹsin rẹ, ẹ̀yà rẹ tàbí ibi tí o ti wá.

11. **Ẹ̀tọ́ láti ní dúkìá** – O lè rà, ní, fún àti ta dúkìá níbikíbi ní Nàìjíríà .

*Àwọn Ẹtọ́ yìí kìí sọ̀rọ̀ orí ahọ́n lásán o -àwọn ni àbò rẹ lọ́wọ́ ìréjẹ àti irinsẹ́ láti kópa.*

# Àwọn ojúṣe rẹ

*(ojúṣe gbogbo ọmọ-ìlù – ìpín kẹrinlélógún(24) Ìwé-Òfin 1999 tí a ṣe àtúnṣe sí)*

Ẹtọ́ ní ojúṣe rẹ. Gẹ́gẹ́ bí ọmọ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, lára ojúṣe rẹ ni :

1. **Se Àpọ́nlé àti dábòbò Nàìjíríà** – Bu iyì fún Ìwé-Òfin, Àsìá, orin àti ipò àṣẹ tó bá òfin mu.

2. **O gbọ́dọ̀ fi ọkàn tán Orílẹ̀-Èdè rẹ** - Tí ó bá pè fún, dá àbò bo Nàìjíríà, kí ó sì lọ́wọ́ sí ìṣọ̀kan àti ìlọsíwájú rẹ̀.

3. **Bọ̀wọ̀ fún Ẹ̀tọ́ àwọn ẹlòmíì** – Gbé ìgbé Àlàáfíà, kí o sì Bọ̀wọ̀ fún iyì gbogbo ènìyàn.

4. **Kópa nínú ìdàgbàsókè àwùjọ** - Kópa nínú ìgbìyànjú láti mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ àti àyíká rẹ.

5. **Bọ̀wọ̀ fún òfin** - E déédéé, kí o sì kún àwọn alá ẹ tí ó wà lábẹ́ òfin lọ́wọ́ láti ṣètò Àlàáfíà.

6. **San Owó-Orí rẹ pẹ̀lú òdodo** – Sọ iye tí ó wọlé fún ọ pẹ̀lú òtítọ́, kí ó sì san iye tó tọ

---

**Kópa nínú ètò Ì ejọba** – **fi orúkọ sílẹ̀** | **yàn** | **dìbò** | **dábòbò tí ó bá ní ìkápá** (**RSVP**), kí o sì máa kàn sí àwọn tí ẹ dìbò yàn.

*Kí ènìyàn jẹ́ ọmọ-ìlù rere ni pé,ohun tí ó tọ́ sí ọ (Ẹ̀tọ́) àti ohun tí ó yẹ kí o ṣe (ojúṣe) kò gbọdọ̀ ju ara wọn lọ.*





2

# Níní òye ìsejọba: ẹ̀ka àti ìpele

*Ní Nàìjíríà, mẹ́ta ni a pín ẹ̀ka àti ìpele ìjọba sí.*

## Àwọn ẹ̀ka ìjọba mẹ́tẹ̀ẹ̀ta

1. **Aláṣẹ** – Wọ́n máa ń gbófin ró, Wọ́n tún máa ń e ètò ìjọba.

    a. **Ìjọba Àpapọ̀:** Ààrẹ àti àwọn Mínísítà.
    b. **Ìpínlẹ̀ :** Gómìnà àti àwọn kọmí ánnà.
    c. **Ìbílẹ̀:** Alága ìjọba ìbílẹ̀ àti àwọn Alábòójútó.



2. **Asòfin** – Wọ́n ń sòfin, fọwọ́ sí ètò ìsúná àti láti jẹ́ olúdọdẹ àwọn aláṣẹ.

    a. **Ìjọba Àpapọ̀** : ilé ìgbìmọ̀ asòfin òkè (àgbà àti kékeré).
    b. **Ìpínlẹ̀** : ilé Asòfin Ìpínlẹ.
    c. **Ìbílẹ̀** : ìgbìmọ̀ ìjọba ìbílẹ.



3. **Amòfin** – láti ṣe agbátẹrù fífi ìdí òfin Múlẹ̀ àti láti yanjú Aáwọ̀ ní ìlànà òfin.

    a. **Àpapọ̀** : ilé-ẹjọ́ Àgbà, ilé-ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn, ilé-ẹjọ́ gíga Àpapọ.
    b. **Ìpínlẹ̀** : Ilé-ẹjọ́ gíga Ìpínlẹ̀ àti àwọn Ilé-ẹjọ́ kéékèèké.



*Àwọn Ẹka yìí dá dúró ní àmọ́ Wọ́n gbọ́dọ̀ le ṣe àmójútó àti àbójútó ara wọn.*

## Àwọn ìpele mẹ́ta tí ìjọba pín sí




1. **Ìjọba Àpapọ** – òun ló ń ṣe àmójútó gbogbo ìlú lórí nǹkan bí ó àbò, àjọ epọ̀ wa pẹ̀lú àwọn Orílẹ̀-Èdè àgbáyé, owó àti kíkọ́ ohun amáyédẹrùn tó bùáyà.
2. **Ìjọba ìpínlè** – ṣíṣe àmójútó Ìpínlẹ̀ lórí n kan bí i ọ̀nà Ilé-ẹ̀kọ́ gíga,Ilé-Ìwòsàn àti ìsúná Ìpínlẹ.
3. **Ìjọba ìbílẹ** – àwọn ló súnmọ́ ará ìlú jù, ojú e wọn ni Ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, Ilé-ìwòsàn ìbílẹ̀, ọjà, ọ̀nà, kólẹ̀-kódọ̀tí àti ìdàgbàsókè àwùjọ.

*Níní àgbọyé lórí ojúṣe ìpele kọ̀ọ̀kan yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti mọ ibi tí wàá darí ìbéèrè rẹ kọ.*



3

# Ẹka Àsòfin

## Ẹka Asòfin àti ọ̀nà tí wọ́n ń gbà sisẹ

*Ẹka Asòfin jẹ́ ìkójọpọ̀sí ará ìlú. Wọ́n ń sòfin, fi òǹtẹ̀lu àbá ìsúná, àti láti jẹ́ ọ̀pá ìbẹ̀rù fún àwọn Aláṣẹ.Àwọn Asòfin jẹ́ a ojú yín – iṣẹ́ yín ni wọ́n lọ jẹ*

## Àwọn ilé ìgbìmọ̀ Asòfin Nàìjíríà

**1**

### Ìgbìmọ̀ Asòfin Àgbà

a. **Ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin**
Oókandínláàdọ́fà (109) Asòfin Àgbà (mẹ́ta ni Ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan, eyọ̀kan ní Olú-ìlú ní Àbújá.

b. **Ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin kékeré**
Ọmọ ilé tó jẹ́ ọ̀taléláàdọ́rùn-ún (360) tí wọ́n ṣojú ẹkùn-ìdìbò kọ̀ọ̀kan àti bí ilẹ̀ wọn ṣe tóbi tó.

**2**

### Ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin Ìpínlẹ̀

a. Ó kéré tán ọmọ Ìgbìmọ̀ mẹ́rinlélógún (24), ó wà bí ará ìlú ṣe pọ̀ tó àti bí ìlú ṣe tóbi tó.

b. Wọ́n ṣe òfin fún ìjọba Ìpínlẹ̀, Wọ́n tún ṣe àbójútó Gómìnà.

**3**

### Àjọ ìjọba ìbílẹ̀ tó ń ṣe òfin

a. Jẹ́ àkójọ àwọn olùgbìmọ̀ tó ń sojú odi kọ̀ọ̀kan.

b. Wọ́n ṣe òfin abẹ́lé fún ìjọba ìbílẹ̀, Wọ́n tún jẹ́ alábòójútó Gómìnà.

## Ohùn tí Ìgbìmọ̀ Asòfin ń ṣe

1. **Ètò Ìṣúná** – Àwọn ni wọ́n fi òǹtẹ̀ lu ètò ìsúná Orílẹ̀-Èdè àti Ìpínlẹ̀.

2. **Ṣíṣe òfin** – Wọ́n ṣe òfin láti mú àlàáfíà, ìlọsíwájú àti ìjọba rere tẹ̀ síwájú.

3. **Ṣíṣasojú** – Wọ́n ṣe òfin láti mú àlàáfíà, ìlọsíwájú àti ìjọba rere tẹ̀ síwájú.

4. **Alábòójútó** – ríri dájú pé ẹ̀ka apàṣẹ fi owó ṣe iṣẹ́ tí wọ́n ya owó fún nínú ètò ìsúná.

5. **Fífi ọwọ́ sí ìyàn sípò àwọn ipò ńlá** – bí Mínísítà, kọmísánnà, Gómìnà ilé-ìfowópamọ̀ àgbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## Bí Àbá-òfin ṣe ń di òfin

1. **Kíkàá ní àkọ́kọ** – àkòrí Àbà-òfin tí Wọ́n bá gbé wá nìkan ni Wọ́n ó kà.
2. **Ìkà èkejì** – àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yóò ṣe à àrò lórí ìlànà òfin náà.
3. **Ìpele ìgbésẹ̀ Ìgbìmọ** – àyẹ̀wò fínnífínní, àtúnṣe tó bá yẹ.
4. **Ìkà ẹ̀kẹta** – ìpinnu Ìgbìmọ̀ àti lílù lóǹtẹ̀ .
5. **Fífiránṣẹ:**
   a. Ní ilé Ìgbìmọ̀ àgbà : fífi ìránṣẹ́ sí ilé Ìgbìmọ̀ kejì (Ìgbìmọ̀ àgbà sí kékeré).
   b. Ní ilé Ìgbìmọ̀ Ìpínlẹ̀ : yóò wà ní ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin.
6. **Fífi òǹtẹ̀ lù** – Ààrẹ tàbí Gómìnà yóò fi ọwọ́ si láti sọ àbá-òfin náà di òfin.
7. **Tí Apàṣẹ bá gbẹ́sẹ̀ le** – àwọn Asòfin le ka ẹsẹ̀ náà kúrò pẹ̀lú ìbò ìdá méjì nínú ìdá mẹ́ta Asòfin.

## Àbójútó irinsẹ́ àwọn Asòfin

1. **Ìbéèrè** – àwọn Asòfin le ṣe béèrè lọ́wọ́ àwọn Apàṣẹ lórí àwọn iṣẹ́ àmúse.

2. **Àbá** – pe àkíyèsí sí ọ̀rọ̀ tó bá súyọ àti ìyànjú.

3. **Ìwádìí àti ìgbọ́rọ** – Ìgbìmọ̀ le ké sí oní  ẹ́, ṣe ìwádìí owó níná àti kí wọ́n pé gbogbo ìlú wá gbọ́rọ.

4. **Mímójútó ètò ìsúná** – ìnáwó kan kò gbọ́dọ̀ wáyé láì gbàsẹ lọ́wọ́ ilé Asòfin.

## Àjọṣe láàárín ará ìlú àti ẹ̀ka Asòfin

1. Ma lọ sí ìgbẹ́jọ́ gbogboògbò, kí o sì sọ èrò tìrẹ.
2. Kọ̀wé sí aṣojú rẹ lórí ọ̀rọ̀ tó ṣe kókó.
3. Mójútó òfin àti ètò ìsúná.
4. Lo ìkànnì bí **ShineYourEye** (lajúrẹ) láti tọ pinpin àti kàn sí a  ojú rẹ.
5. Bẹ aṣojú rẹ wò ní ọ́fíísì ẹkùn ìdìbò.

*Ará-ìlú  ló ni ẹ̀ka Asòfin. Tí àwọn ará-ìlú ò bá kópa, òfin àti ètò ìsúná ò ní jẹ mọ́ ohun tí wọ́n nílò*



# 4 Ọ̀nà láti fa aṣòfin wálé




*Fífa Asòfin wá ilé jẹ́ ọ̀nà tí àwọn ọmọ-ìlú le gbà yọ Asòfin tí a dìbò yàn nípò kí sáà rẹ̀ tó tán tí wọ́n kò bá ṣojú  àwọn ènìyàn bí ó ṣe yẹ. Ó jẹ́ lára àwọn ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn ọmọ-Ìlú lò láti jẹ́ kí àwọn Asòfin ṣe ìṣirò*

## Ìgbésẹ̀ láti fà Asòfin wálé

### 1. Tí àwọn olùdìbò bá bẹ̀bẹ̀ fun



a. Tí àwọn olùdìbò tí ó forúkọ sílẹ̀ bá kọ ìwé ìfẹ̀sùnkàn ìdí tí wọ́n fi fẹ́ pe Asòfin wálé.

b. Ó kéré tán, ìdá adọ́ta nínú ọgọ́rùn-ún nínú àwọn olùdìbò tí ó forúkọ sílẹ̀ gbọ́dọ̀ fi ọwọ́ sí ìwé náà.

### 2. Fífún ìwé ẹ̀sùn ránṣẹ́ sí Àjọ Olómìnira tó ń ṣètò ìdìbò INEC



a. Lílọ fún àjọ elétò ìdìbò (INEC) ní ìwé ẹ̀sùn náà.

b. Àjọ INEC yóò jẹ́rìí àwọn ìbuwọ́lùwé náà bóyá tí àwọn olùdìbò tí ó forúkọ sílẹ̀ ní ẹkùn ìdìbò náà ni.

### 3. Ìbò bẹ̀ẹ̀ni tàbí bẹ́ẹ̀kọ



a. Tí ìjẹ́rìí náà bá yege, Àjọ Olómìnira tó ń ṣètò ìdìbò (INEC) yóò ṣe ètò ìdìbò bẹ́ẹ̀ni tàbí bẹ̀ẹ̀kọ́ ní ẹkùn ìdìbò náà.

b. Wọn ó bi àwọn olùdìbò tí ó forúkọ sílẹ̀ pé, " ṣé ẹ fẹ́ kí Asòfin yìí kó máa bọ̀ nílé?"

c. Tí Àwọn tó ju ìdá adọ́ta nínú ọgọ́rùn-ún bá sọ pé BẸ́Ẹ̀NI, Asòfin yẹn ti wálé nìyẹn.

## Ta ni a lè fà wálé?

1. Ọmọ ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin òkè (àgbà àti kékeré) ní Àbújá.

2. Ọmọ ilé Ìgbìmọ̀ Asòfin Ìpínlẹ̀.

*A kò le fa Gómìnà tàbí Ààrẹ wálé. Wọ́n lè yọ àwọn nípò ni. A kò le fa àwọn oní  ẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ náà wálé.*

## Ìṣòro tó ń dójú kọ fífa Asòfin wálé ní Nàìjíríà

1. Gbígba ìfọwọ́bọ̀wé ìdá adọ́ta nínú ọgọ́rùn-ún àwọn olùdìbò jẹ́ ìṣòro gan-an.

2. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ-Ìlú ò mọ Ìgbésẹ̀ náà tàbí agbára wọn láti lò ó.

3. Àwọn Olóṣèlú sáábà máa ń lo owó, ipò tàbí agbára láti da ètò fífa wọ̀n ọ́n wálé rú.

4. Kò tíì sí Asòfin kankan tí wọ́n fà wálé láti òkè rí.

## Ìdí tí ètò fífa Asòfin wálé ṣe pàtàkì

1. Bó ti wulẹ̀ kò burú tó, fífa Asòfin wálé jẹ́ ká mọ agbára òfin tí ọmọ-ìlù ni lórí àwọn a  ojú.

2. Ètò fífa Asòfin wálé pé àwọn ènìyàn sí àkíyèsí, tí ó sì le ṣokùnfà kí Asòfin hùwà dáadáa.

3. Ó ń kọ́ àwùjọ láti kórajọ, foríkorí, fikùnlukùn àti láti béèrè fún ìṣirò iṣẹ.

*Fífa wá ilé jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà bí ï – ìwé ẹ̀sùn , ìfẹ̀hónú hàn, ìgbẹ̀jọ́ ìta-gbangba àti ìpolongo ọmọ-ìlù tí a lè lò láti mú àwọn olórí wa ṣe ìṣirò.*




5

# Àwọn Ohun èlò ìkópa ọmọ-ìlù

*Ìjọba Alágbádá kìí ṣe pé a wá wo ìran Eré-Ìdárayá. Àwọn ọmọ-Ìlú ní ẹ̀tọ́ àti ojúṣe láti kópa nínú ètò Ìṣejọba. Àwọn irinṣẹ́ yìí yóò ràn wá lọ́wọ́ láti ṣe ìpín rẹ dáadáa.*

## Shine Your Eye (La ojú rẹ dáadáa)

### Wá aṣojú rẹ kan, kí o sì ni àsopọ̀ pẹ̀lú rẹ

1. Kàn sí ***www.shineyoureye.org***.



2. Tẹ nọ́mbà ilé ìdìbò rẹ sì, tàbí kí o wá ìjọba Ìpínlẹ̀ àti ìbílẹ̀ láti rí bí o ṣe lè kàn sí aṣojú rẹ ní gbogbo ìpele.
3. Ṣe àwárí nọ́mbà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ wọn, Àtẹ̀jíṣẹ́-tayárabíáṣá wọn àti ọ̀nà mìíràn tí ẹ le fi kàn wọ́n lára.
4. Fi ìròyìn yàjóyàjó síta kí àwọn ọmọ ìlú le jẹ à fààní ẹ̀kọ́ nǹkan tó ṣe déédéé. *(syeinfo@eienigeria.org)*.

*Ìjọba àwarawa ṣiṣẹ́ dára jù lọ tí àwọn ọmọ ìlú bá mọ àwọn aṣojú wọn tí wọn sì ń kàn sí wọn.*

RSVP — REGISTER | SELECT | VOTE | PROTECT

## Láti kópa: fi orúkọ sílẹ̀ | Yàn | dìbò | dábòbò

1. **Fi orúkọ sílẹ̀** – ri dájú pé orúkọ rẹ wà lórí ìwé àwọn olùdìbò, kí o sì ní káàdì ìdìbò alálòpẹ́.
2. **Yàn** – má tẹ̀lé ọ̀rọ̀ ẹnu nìkan, yẹ ìwà olùjíde wò fínnífínní, ṣe ó kó ojú òṣùwọ̀n?, ṣe ó ìkápá?, ṣe ó ní ojú àánú?

3. **Dìbò** – jáde wá dìbò ní ọjọ́ ìdìbò.

4. **Dábòbò** – dúró di ìgbà tí wọ́n fi ka ìbò tán,fi ẹjọ́ mọ̀kàrú sùn kí o sì tẹ̀lé èsì ìbò.

*Kí kópa kìí ṣe fún ọjọ́ ìdìbò `nìkan – ohun gbogbo ìgbà ni láti kí ìdìbò tó dé, ìgbà ìdìbò àti lẹ́yìn ìdìbò.*

## Káàdì ìdìbò aláìlópin (PVC): Fífi orúkọ sílẹ̀ àti bíbá ìgbà mu

Lọ sí ***cur.inecnigeria.org*** tàbí ọ́fíísì Àjọ Olómìnira tó ń ṣètò ìdìbò INEC láti lọ:

1. Fi orúkọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bi olùdìbò tuntun.
2. Yẹ orúkọ ìdìbò rẹ wò bóyá wọ́n kọ ọ́ dáadáa.
3. Gbé ilé ìdìbò rẹ lọ àdúgbò tuntun tí o kó lọ.
4. Ṣe àtúnṣe sí àṣìṣe orí àtẹ ìdìbò rẹ.
5. Gba káàdì ìdìbò alálòpẹ́ rẹ tó bá ti jáde.
6. Lọ gba káàdì mìíràn tí tọwọ́ rẹ bá sọnù tàbí bàjẹ́.

*Àjọ elétò ìdìbò (INEC) le dáwọ́ ìforúkọ sílẹ̀ dúró ní àwọn àkókò kan ( bí àpẹẹrẹ tí ìdìbò bá súnmọ). Ó gbọ́dọ̀ máa yẹ orí ayélujára tàbí ọ́fíísì àjọ elétò ìdìbò tó súnmọ́ ọ wò fún ìró tuntun.*




Gbàrà tí o bá ti pé ọmọ ọdún méjìdínlógún (18), o ti lẹ́tọ̀ọ́ láti forúkọsílẹ̀ kí o sì dìbò ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Bí o kò bá forúkọsílẹ̀, o kò ní lè dìbò; àwọn ẹlòmíràn ni yóò sì pinnu ẹni tí yóò ṣojú àdúgbò rẹ, ìjọba ìbílẹ̀ rẹ, ìpínlẹ̀ rẹ, àti orílẹ̀-èdè rẹ lórí àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ire rẹ.

*Nọ́ńbà ibùdó ìdìbò rẹ (PU number) wà ní apá òkè lọ́wọ́ òsì.*
*Nọ́ńbà ìdánimọ̀ rẹ (VIN) ni nọ́ńbà tó wà ní apá òkè lọ́wọ́ ọ̀tún lórí káàdì ìdìbò (PVC) rẹ.*

## Mímójútó ètò ìdìbò



1. Dúró ní ilé ìdìbò títí tí wọ́n ó fi ka ìbò tán.
2. Pín ẹ̀dà èsì ìdánwò ní àdúgbò rẹ.
3. Fífi ìṣẹ̀lẹ̀ mọ̀kàrú sun àjọ ètò ìdìbò pẹ̀lú ago pàjáwìrì tí wọ́n fi síta tàbí àwọn fi sún àwọn àjọ ará ìlú lórí àtẹ wọn.
4. Máa ṣe ta ìbò rẹ- ìbò rẹ ni ohùn rẹ.

## Àwọn irinṣẹ́ àjọ ará ìlú mìíràn tó wà lórí ayélujára ni *(láti ọwọ́ àjọ EiE ti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti àwọn olùkù wọn)*

1. **LearnPolitics.ng** – a ń pèsè ẹ̀kọ́ kún-rẹ́rẹ́ nípa òṣèlú.
2. **#MissingInNG (governi.ng)** – wíwá àti fífi ẹjọ́ ẹni tí à ń wá sùn.

3. **Podus AI** – kọ àwọn ìwé òfin, yanjú ìṣòro, kí o sì rí àwọn amòfin. Fi iṣẹ́ ránṣẹ́ sí 07067951851 lórí WhatsApp láti bẹ̀rẹ̀.
4. **Tracka.ng** – sọ, tọ pinpin àti ìwádìí iṣẹ́ àkàn  e tó yẹ kí wọ́n ṣe, tàbí tí wọ́n ṣe lọ́wọ́ àbí t í wọ́n ti kọ̀ silẹ̀ ní agbègbè rẹ.
5. **Govspend.ng** – tọ pinpin iye tí ìjọba Àpapọ̀ fún àwọn àjọ, ìsọ̀rí, àti ẹ̀ka rẹ. Tọ pinpin àwọn tí ó gba ìṣẹ́ àkànṣe àti àwọn tó gba owó ìjọba.

*Ìkànnì yìí mú ètò Ìṣejọba súnmọ́ – ṣe àmúlò rẹ láti mọ̀ àti láti kópa.*

# 6 Atọ́nà àti oríṣiríṣi àpẹẹrẹ

*Ìjẹ́ ọmọ-ìlù ju kí a mọ Ẹ̀tọ́ wá lọ - bí kò ṣe ká lò ó. Káàkiri Nàìjíríà, àwùjọ ti ń kó jọ, ti ń ṣe ìbéèrè, Wọ́n ti ń jẹ kí àwọn olórí sisẹ́. Àwọn ìtàn jẹ́ ká mọ nǹkan tó éesé tí àwọn ọmọ-Ìlú bá kópa.*

## Àpẹẹrẹ àyẹ̀wò àkọ́kọ́:
## Pípèsè omi mímọ́ fún àwọn tí ogun lé nílé abẹ́lé (myLGA)

Ní ìlú Ugya ìjọba ìbílẹ̀ Toto (Ìpínlẹ̀ Násáráwá), àwọn ìdílé tí ogún lé nílé ní ìṣòro omi. Wọ́n ń kó àárùn láti ara omi odò tó ń ṣàn àti kànga. Ní oṣù kẹfà (ògùdù) ọdún 2025, pẹ̀lú ìkúnlọ́wọ́ EiE #OOTCHelpDesk, ẹ̀bẹ̀ wọn dé etí alága ìjọba ìbílẹ̀. Wọ́n pèsè omi kànga jingodo fún àwọn èèyàn náà, tí èyí sì ń pèsè omi tó mọ́ tó ṣe mú fún àwọn ara ìlú fún ìgbà àkọ́kọ.

**Ẹ̀kọ́:** ìṣòro tó burú ju le rí àtúnṣe tí àwọn ọmọ-Ìlú bá sọ̀rọ̀-sókè tí àwọn olórí bá sì tẹ́tí gbọ.

## Àpẹẹrẹ àyẹ̀wò kejì:
## Àtúnṣe Ilé-ẹ̀kọ́ ní Zamfara (rédíò ọ́fíísì ọmọ ìlú)

Ní ìlú Birni Ruwa, Ìpínlẹ̀ Zamfara àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ń kọ́sẹ́ nínú yàrá tó ti fẹ́ wó, tí òrùlé rẹ̀ ń jò láì tún ní àga àti tábìlì. Ní ọdún 2019,lórí ètò tí ọ́fíísì EiE ń ṣe lórí rédíò fún àgbègbè náà láyé láti sọ̀rọ̀. Ọ̀ rọ̀ náà tàn káàkiri gbogbo Ìpínlẹ̀, àwọn oníṣẹ́ ìjọba wá ṣe àbẹ̀wò tí wọ́n sì gbé iṣẹ́ àtúnṣe náà síta. Lónìí, wọ́n ti tún Ilé-ẹ̀kọ́ náà ṣe, tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sì ń gba ẹ̀kọ́ ní ibi tó fọkàn balẹ

**Ẹ̀kọ́:** ìkéde kan ti tó láti rí ẹ̀kọ́ fún ọmọ ọgọ́rùn-ún.

## Àpẹẹrẹ àyẹ̀wò kẹta:
## Ìṣẹ́gun fún àwọn ọlọ́kadà ní Ìpínlẹ̀ Enugu (rédíò ọ́fíísì ọmọ ìlú)

Ní ìlú Emene-Nkwuborn ní ìjọba ìbílẹ̀ ìlà-oòrùn (2019), àwọn ọlọ́pàá ń lo òfin òfegè pé, ọ̀kadà ò gbọdọ̀ rìn, wọ́n sì puró gba owó lọ́wọ́ àwọn ọlọ́kadà. Lórí rédíò OOTC, àwọn ọlọ́kadà sọ ohun ojú wọn ń rí lórí ètò, EiE fi tó kọmísọ́nà ọlọ́pàá létí, kíá ló pàṣẹ kí wọ́n tú gbogbo ọ̀kadà náà silẹ̀, ó fi òpin sí ìlọ́nilọ́wọ́gbà, ó sì bẹ̀rẹ̀ ìwádìí.

**Ẹ̀kọ́:** tí a bá tú àṣírí ìrẹ́jẹ, kódà àwọn àjọ tó ní ìkìmí ó gbé Ìgbésẹ.

## Àpẹẹrẹ àyẹ̀wò kẹrin:
## Títají ètò ìwòsàn ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀sun (rédíò ọ́fíísì ọmọ ìlú)

Káàkiri gbogbo Ìpínlẹ̀ Ọ̀sun, Ilé-ìwòsàn tó dẹnukolẹ̀ ò jẹ́ kí àwọn ènìyàn rí àǹfààní ìwòsàn. Ní 2019, rédíò OOTC tọ́ka sí ìbàjẹ́ náà. Ìjọba dáhùn bí wọ́n ṣe bẹ̀rẹ̀ àtúnṣe, tí èyí sì fún ogunlọ́gọ̀ ará ìlú ní àǹfààní sí ìwòsàn.

**Ẹ̀kọ́:** ohun ọmọ ìlú le dá eto ìwòsàn padà sínú ètò ìlú.

## Ọ̀nà àmúlò láti kópa

1. Ẹ gbọ́dọ̀ kọ gbogbo ohun tí ẹ fẹ́ sínú ìwé (lẹ́tà, ìwé ẹ̀sùn , kí á tẹ̀ ẹ́ sí orí ẹ̀rọ ayélujára).
2. Ẹ sisẹ́ pọ̀ bí ikọ̀ – ohùn ikọ̀ máa ń rinlẹ̀ju ohùn ẹnìkan lọ.
3. Ẹ tọ́ọ̀ déédéé, ṣíṣe ìṣirò máa ń gba àkókò.
4. Lo ilé-isé ìròyìn àti ẹ̀rọ ayélujára láti yín ohùn yín sókè.
5. Ẹ gbọ́dọ̀ wà ní àlàáfíà, kí ẹ sì tẹ̀lé òfin nínú gbogbo ohun tí ẹ bá ń ṣe.

# Ohun Èlò àti àwọn tí a lè kàn sí

*Gẹ́gẹ́ bí ọmọ ìlú tó ní ìgbìyànjú, má dàá gbé Ìgbésẹ̀. Ìkànnì àti àwọn àjọ yìí máa kún ọ lọ́wọ́ pẹ̀lú ohun èlò.*

## Ìkànnì EiE Nàìjíríà

1. **ShineYourEye.org** – wá kí o sì kàn sí aṣojú tí ẹ dìbò yàn.
2. **myLGA.ng** – mọ nípa ìjọba ìbílẹ̀ rẹ kí o sì máa tọ pinpin wọn.
3. **#MissingInNG** (governi.ng) – sọ, kí ẹ sì wá ènìyàn tí ẹ ń wá.
4. **RSVP.ng** (Civic education) – ẹ̀kọ́ nípa ti ìlú: fi orúkọ sílẹ̀, mú, dìbò, dábòbò.
5. **eienigeria.org** – kàn sí Ẹ̀kọ́ nípa ti ìlú wa, ìgbàwí wá àti ohun èlò ìpolongo wá.

| Àjọ /Ìkànnì | Ohun tí wọ́n gbájumọ | Bí a ṣe lè kàn sí wọn |
|---|---|---|
| **INEC** | *Mímójútó ètò ìdìbò, gbígba orúkọ olùdìbò sílẹ̀, káàdì alálòpẹ́ PVC, èsì ìdìbò.* | *www.inecnigeria.org cur.inecnigeria.org* |
| **Tracka** | *Sọ, ṣe àyẹ̀wò, tọ pinpin iṣẹ́ àkànṣe tí wọ́n ń ṣe, tí wọ́n ti ṣe àti èyí tí wọ́n pàtì.* | *Irinṣẹ́ Tracka.ng lórí ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ yin (ó wà lórí IOS àti ìkànnì Áńdírọ̀dù).* |
| **Govspend** | *Ṣe àmójútó pàtó iye tí ìjọba Àpapọ̀ fún àwọn Ẹ̀ka,ìsọ̀rí àti àjọtó gba owó àti iṣẹ́ àkànṣe lọ́wọ́ ìjọba.* | *www.govspend.ng* |
| **Podus AI** | *Kọ ìwé òfin, yanjú ìṣòro kí o sì gba agbẹjọ́rò.* | *Tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ sí nọ́mbà yìí 07067951851 lórí ìkànnì WhatsApp.* |
| **Yiaga Africa** | *Ṣe àmójútó ètò ìdìbò, kún àwọn ọ̀dọ́ lọ́wọ́ láti kópa, #NotTooYoungToRun.* | *www.yiaga.org* |
| **CLEEN Foundation** | *Ètò àbò, àtún e ẹ̀ka ìdájọ́, mímú ọlọ́pàá ṣe ìṣirò.* | *www.cleen.org* |

*Ìwé ìléwọ̀ jẹ́ àkójọpọ̀ gbogbo àkóónú ohun èlò ìkọ́ni nípa ìlú tí EiE Nàìjíríà tí ó ní ìwé ìdánimọ̀ ọmọ-ìlù, Ìwé-Òfin 101, ìwé ìdánimọ̀ Asòfin àti ọ̀nà láti fa Asòfin wálé. A pelò rẹ láti lò ní ìrọ̀rùn fún àwọn mẹ̀kúnnù.*

# Ìtẹjáde







www.eie.ng/resources/publications/

# Ìtẹ̀jáde







www.eie.ng/resources/publications/

*Developed and designed by Enough is Enough Nigeria | October 2025*